# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

VOL. XIV NO 814 LAGOS SATURDAY APRIL 7. — APRIL 13. 1962 KOBO MEJI (2D)


# Ijoba Ghana Fe Le Awon Alejo Kora To Nse Ise Fayawo Jade Nilu

ACCRA - Ni Ijẹta, ti ṣe ọ'jọbọ, ni awọn ọlọpa ilu Ghana, ni Oke Okun, gbe ogun ko awọn ajoji ti nwọn npe ni KỌRA ti nwọn nṣe iṣẹ owo (trade) kakiri ilu na, lori ẹsun ti pe, nwọn nṣe iṣẹ FAYAWỌ mọ iṣẹ wọn ; o to adọjọ enia ti nwọn fi si itimọle.

Ijọba Ghana na si tun ṣe ikede wipe awọn ti ṣ'akiyesi wipe ọpọlọpọ awọn alejo KỌRA na lo ti fi iṣẹ fayawọ ko gbogbo ohun ọla, bi golu ati dayamọnu ilu awọn lọ si ilu ajoji, ti nwọn si ni owo tabua ninu awọn Banki ilu okere. Nwọn ni awọn ti ṣe ipinnu lati wa awọn oniṣẹ buruku ninu awọn alejo na kuro nilu, awọn yio jẹki nwọn ta awọn ẹru wọn ati ile ti nwọn ba ni ṣugbọn owo ti nwọn yio kuro nilu ko gbọdọ ju iye ti ofin wi lọ.



## Egbe Atun Oja Koko Se

Ilẹ Nigeria yio pẹlu awọn ilu bi mẹrin Ghana, Brazil, Cameroun Republic ati Ivory Coast lati da ẹgbẹ kan silẹ ti yio ma tun owo ọja Koko ṣe, nitori owo ọja Koko na njo r'ehin nigbakugba. Gbere rẹ! ni gbọgbọ ile igbimọ wi.

Ọrọ yi ni Alase Owo ati Isọwọ, Zanna Bukar Dipcharima sọ ninu ile Igbimọ Apapọ lori eto itọju ilu fun ọdun mẹfa.

## Egbe Omo Ilorin Mushin Koiti Fidimule Daradara

Ni ana ọjọ Jimọ ni ọpọlọpọ awọn ọmọ ilu Ilọrin, awọn ọmọ oko Ilọrin ati diẹ ninu awọn ọmọ Igbomina, Ologbondoko ati Oke-Ọdẹ ti nwọn ri i pe awọn ba ara Ilọrin taa ni ti ẹbi, lọ si ibi ipade ẹgbẹ kan ti nwọn ni nwọn fẹ da silẹ ni Mushin. Ọpọlọpọ wọn gba ile eniti nwọn pe ni baba ẹgbẹ na ni Abẹokuta Street, Mushin, ki nwọn to tun dari wọn si ọna ile alaga ni Paul Okuntọla Street, eti ọja Mushin,

Ọpọlọpọ awọn ti o wa si ipade na ni nwọn ṣe akiyesi pe kosi eto wipe ipade wa fun ẹgbẹ lọjọ na. Ṣugbọn ninu nwọn fi ọrọ jẹ omitoro-ọrọ, ni ẹnikan ninu awọn ti o wa si ibi ipade na f'ọrọ ye ni pe ẹgbẹ na kosi fun amuna awọn, afi awọn ọmọ ti nwọn ba bi si adugbo ilu Ilọrin bi Idi-aro, Ọja Ọba, Idi Apẹ, Isalẹ Gada tabi Oke Pakata ni nwọn le wọ ẹgbẹ na. Ẹnikan si tun fiye wọn wipe a fi onte tẹ iwe orukọ ẹgbẹ yi lọdọ Ijọba ko wipe ki awọn ẹlomiran l'Eko, ni Agege tabi l'Abẹokuta ma le pe ẹgbẹ ti wọn na ni Ẹgbẹ Ọmọ Ilọrin mọ.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY WARRI SAPELE,
ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell
Telephone London Wall 4303
Cable & Telegrams Natbaniger ; London
Head Office Representatives in London.
E. Akinwunmi Doherty,
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURGH

# AWORAN TITUN TI OMO'BA PHILIP

**Aworan ti a nwo yi niti Ololajulo Omo'ba Philip ti ise oko Alaiyeluwa Oba'binriu Elizabeth Keji, ti ilu Oyinbo Ges'.**

**Ololajulo na fi ile sile lo rin ile iha Gusu Amerika wo, o gba ile British Guiana, Venezuela, Colombia, Ecuador, Peru, Bolivia, Chile, Paraguay, Uraguay, Brazil ati Argentina.**

**Ninu irin re na Ololajulo Omo'ba Philip ni o toko ofurufu ti a npe ni "Dart Herald" ti o mu lo.**



## Boisson Honours Brossette



Picture shows Mr. Alex Ola Oni, Monsieur Henry Brossette and Monsieur Felix Houp-Houet Biogney, Ambassador Ivory Coast at the reception which was held at the Federal Palace Hotel Lagos.

# Ode To P'efon Gba ojo Iku

CALABAR - Laipẹ yi ni ọdẹ kan ti o njẹ Hanson Esien, lọ sinu igbo'malẹ kan ti nwọn npe ni Ikot Okoyo lati ṣe ọdẹ eran - pipa, bi o ti de ibẹ ni o ri awọn ẹfọn meji, ti o si yin'bọn si wọn, o pa wọn ni apafọn, ṣugbọn ni ẹsẹ kanna ni ibọn ọwọ rẹ bọ silẹ, ti on na si ya odi, ti ọwọ ati ẹsẹ rẹ si rọ bi ewe. Bi nwọn ti ru u wọ abule ni o si ku.

Ọgbẹni Isang Ekpe ti o ba ọdẹ na lọ sinu igbo ni ikan ninu awọn ẹfọn na lọgun gbẹẹ, ohun rẹ si dabi t'enia nigbati ibọn bua. Enikan ninu awọn Olori abule na ni lojọ ti alaiye ti de aiye awọn kii dẹ igbo na nitori igbo awọn iwinlẹ ati alijonnu buruku ni, ọdẹ yi si ti nṣe iṣẹ ọdẹ o to ọdun mẹwa.

# ALATISE NI MO ATUNSE ARA RE

(Lati ọwọ Latifu Babalọla)

Nì igba lailai, ọkunrin kan wa ti orukọ rẹ ma njẹ Adio, Adio jẹ ẹniti Ọlọrun da lọla, o lowo, o si ni iyi pupọ larin ilu.

Nigbati o ṣe, Adio gbe iyawo kini, nigbati o tun pẹ diẹ o gbe iyawo keji, iyawo akọkọ bi ọmọ to mẹfa fun Adio, ṣugbọn iyawo keji ko bimọ rara.

Lẹhin ọdun diẹ, adanwo buruku de ba Adio, oju rẹ mejeji fọ, oko rẹ si tun ku, ko le ṣe'ọkọ obinrin mọ. Eyi mu inu rẹ baje gidigidi, o si ba awọn iyawo rẹ mejeji ninu jẹ papa eyiti koiti bimọ rara.

Ninu ipo ibanujẹ nlanla yi ni Adio wa, ni o dede ṣebi en pe ẹiyẹ nla kan ati kekere kan nle ara wọn bọ wa si ọkankan ibiti on joko si gan-ran, laifa ọrọ lọ titi, ẹiyẹ kekere kan sawọ inu apo A [illegible] ẹiyẹ nla duro si okere o nw[illegible] Ọkẹrẹ gun ori iroko oju ọdẹ da.

Olukuluku ṣa loni ẹbun tirẹ. Ẹlomiran ni ẹbun afọṣẹ ṣugbọn Adio yi ni ẹbun gbigbọ ohun awọn ẹiyẹ, kini ohun ti Adio ma gbọ ti ẹiyẹ nla ti o nle kekere bọ wa wi ? o pee o ni bi iwọ ọkunrin yi ba le mu ẹiyẹ kekere yẹn fun mi pajẹ kia ni oju rẹ yio la. Bi Adio ti gbọ eyi tan bẹni ẹiyẹ kekere tun fesi pe iwọ Ọgbẹni yi bi iwọ ko ba mu mi jade fun ẹiyẹ nla pajẹ, lọgan ni oko rẹ yio ma ṣiṣẹ.

Nigbati Adio tun gbọ eyi idamu ba a, ko mọ eyiti yio ṣe mọ, ile aiye ko ṣe gbe ọna ko si pe mẹta, ewo ni ṣiṣe ? Idamu yi bo tobẹgẹẹ, ti Adio fi ranṣẹ si iyawo kini pe bayibayi ni ẹiyẹ akọkọ wi, ati bayibayi ni ẹiyẹ ekeji wi, nitori idi eyi ki iyawo na fun on ni imọran ohun ti on yio ṣe. Iyawo dahun pe imọran ti on ni pe ko ni ṣiṣe ko ni aiṣe ko tete mu ẹiyẹ kekere fun nla pajẹ, nipa bayi oju rẹ yio la.

(Wo yoku loju ewe karun)


# CARSON PAINTS AND FANISHES



SOLE AGENT
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street, Lagos.


# Odomokunrin Kan Para Re Nitori Ise

Okitipupa-Laipẹ yi, awọn ọlọpa ilu Akurẹ ni lati fi agbara ṣi ilẹkun iyara ọdọmọde-kurin kan ti o njẹ Godfrey Ditan, ti o pokunso sinu yara kan ni Ita Kalẹ, nitoripe ko si iṣẹ lọwọ rẹ.

Onirohin wa fi ye wa wipe, ki ọmọde-kunrin na to fi okun si ara rẹ l'ọrun, o kọ iwe-akọsilẹ kan si ọrẹ rẹ Thomas Ayọdeji, ninu eyiti o wipe, lati ọdun kẹwa ti on ti jade ile'we on ko ri ẹnikan gba on siṣẹ rara; o di ẹgbẹrun o le diẹ iwe-anwa'ṣẹ ti on kọ kakiri ibi iṣẹ ti on ko ri esi.

O ni bi on ba kuku ku, o yaju iya ti on njẹ ninu aiye lọ. O ni iwe-ẹri ti on gba nigbati on jade ile-ẹkọ wa lọdọ awọn Oyinbo onigẹdu kan ti nwọn njẹ Brandler and Rylke, Timber Company Limited, ni Ondo. O ni on ṣeṣẹ fi iwe na ṣọwọ si nwọn nigbati on wa iṣẹ kiri ni.





ELETI-OFE

D'ARABA

ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosọkọ Street, Lagos. "ELETI ỌFẸ," LAGOS.

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 814. SATURDAY APRIL 7 - APRIL 13, 1962

# "ARA ILE ENI L'O NSENI ....

EBITI ko p'era", ni owe awọn Yoruba ti a r o si etọ lati fi ṣe akọle wosika wa ọsẹ yi fun enyin ọkawe wa, lori ọ r ọ " I f a r a d a e d i n w o iṣe" (Austerity Measure) ati afikun owo 'Bode ti Ijọba Apapọ ṣeṣẹ gbe jade yi.

Ikede na fẹrẹ maiti jade tan ti awọn Onişowo, awọn oluta ọja ohun jijẹ ti bu kun owo ọja kakiri ilu, ti o fi de ilẹ Ariwa a t i Iwọ-orun. Paapa awọn onişọbu ti o nta ọti Bia ati awọn n k a n bẹbẹ ẹ ni nwọn ti yara bukun owo wọn. I r u f ẹ iwa bawọnyi kole ṣe ilu wa ni anfani.

Lọna kini, awọn Alaṣẹ Ijọba wa nfẹ lati le ri owo fi ṣe iṣẹ anfani ati ilọsiwaju fun i l u wa k i o le duro gẹgẹbi awọn i l u ominira m i r a n nilẹ okere, ṣugbọn, kọntan ki a gbiyanju lati ni ifarada diẹ fun ire ilẹ wa, ọna inira ni a tun nwa fun'rawa, eyi ni ohun na ti o mu wa fi owe awọn Yoruba yi ṣe akọle aṣaro ọrọ wa ọsẹ yi.

" Ara ile eni l'o nseni, ebiti ko p'era".

# OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA ỌMIRAN, EYI NI OGUN T' ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA.

BI IṢU AKARA GBIGBONA

**E Polowo Oja Nyin**

**Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe**

# Iwe Si Olotu

## Oro Ayiluka

Olotu,

Ẹ jọwọ, ẹ gba mi laye ninu iwe irohin nyin "Eleti-Ọfẹ" lati kan sara si akọwe yin, Ọgbeni Ayiluka, fun ọrọ rẹ ti o ma nfi dawa lara ya lọsọsẹ. Ki a ko t'ẹlẹgan kuro, ọrọ Ayiluka na f'ọpawọn ni.

O to iwọn ọdun marundinlogoji (1927) ti mo ti nka iwe irohin "Eleti-Ọfẹ" iyẹn nigbati ilu Ekokoi ti di bọda-o-wa, t i ọmọde mọagba l'ẹgbọn, ti jamba iku mọto ko pọ pupọ to eyi.

Olotu, mo bẹ nyin pupọ, ki ẹ ba wa sọ fun Ọgbẹni Ayiluka na ki o fi ẹsẹ kan de ilu awọn baale mi ni Ekiti, baya o le ri irohin aladun muwa fun wa, 'Ọpọlọ ni ọrọ ọkọ janto-janto ni o."

Emi ni,

Surulere BỌLAJOKO

## Alhaji Maito, o ku Orire

Olotu,

Inu ọpọlọpọ awọn enia l'odun lati ri i ka ninu i w e irohin nyin wipe Ogbeni wa Alhaji Maito ati diẹ ninu awọn ọmọlẹgbẹ rẹ ti nwọn sọ s'ẹwọn ti jare ẹjọ kotẹmilọrun ti wọn pe Ijọba.

Nisisiyi ti nwọn ti lo ẹwọn wọn tan ki nwọn to jare ẹjọ na, kini awọn Ijọba Ilorin yio ṣe fun wọn? Emi ki iṣe ọmọ ẹgbẹ oṣelu kankan, ṣugbọn mo ri wipe o yẹ, o si tọ ki awọn Olotu Ijọba na fi owo diẹ rẹwọn lẹkun fun ijiya ti oju wọn ri ninu ọgba ẹwọn na.

Ẹ ṣe pupọ, e ku i b a w a mojuto ilu wa na.

Emi ni,

Ilọrin Y. IYANDA

# Won Fi Olopa Sun Esun Agbowo-Ehin

KADUNA-Ọkunrin ọlọpa kan ti orukọ rẹ n j ẹ Cunningham Numan, ni a gbọ wipe nwọn fi sun ẹsun pe o gba owo-ẹhin ṣile kan (1/-bribe).

Onidajọ fi gbigbọ ẹjọ rẹ si ọjọ kẹsan oṣu April 1962.

**Plushes, Velvet, Velveteens, Damask**

**& Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

( 63, Massey Street, Faji Market )

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranted.

# Nihin, Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

Ayiluka nki yin o. Ọrẹ mi. Oloye Okotie-Ebo k' o w o tuntun de, bi o ti nko owo tuntun wọ ilu, bẹni o nfi i s o tuntun bẹ ẹ. "OMIMI-EJO'. mo kan sara si ẹ fun ti owo ọti biya ati aṣọ aran ti o fi kun owo-bode wọn. Nitotọ ni awọn Ijọba Apapọ nwa sile tabua lati na fun idagbasoke nkan ilu, ṣugbọn ki iṣe ki a bẹgi lori awọn nkan onjẹ bi tii ati lori ẹran ati adiẹ.

Boya "Omimi-Ejo", niran ileri ti a ṣe niwọn nkan bi ọdun mẹtadin-logun sẹhin, ninu ile-ere kan ti a npe ni Yaba R e x Club, ti Ọgbẹni Alfred Riwane nṣe Alakoso rẹ, ni akọkọ lọ silu Oyinbo Omimi-Ejo na ? ti emi Ayiluka ati awọn e n i a jankan-j nkan bi Ologbe Mbonu Ojike wa sibẹ. A ni bi a ba gba Ominira Ijọba wa, a ko ni ra ọja awọn ajoji to bẹ mọ. (We shall boycott all the boycottables).

A ko lo ọti oyinbo (Bia) lọjọ na. ẹmu ati ogurọ n i a mu ni amu gbadun, ahua (igba imumi) ni a lo, a k o l o tombila rara. Nigbana Oti Ogogoro koi ti ẹpọ l'Eko. Warri ati Sapẹlẹ ni nwọn ti nmu wọlu, boya a ba ri awọn ti o fẹ mu u ninu wa lọjọ na.

Ju gbogbo rẹ lọ Omimi Ejo, kiloṣe ti oju rẹ fifo owo-bode lori ọti Ogogoro" ? Boya o ko mọ wipe ogunlọgọ awọn buradа wa li o nmu ni Burutu, Fọkadosi Warri, Sapele ati ni Apapa Ajegunlẹ. Ki a ma purọ, ọti Ogogoro lagbara ju Wisiki lọ.

J.M.J. ỌLỌJỌ-IBI

Orukọ Apapa Ajegunlẹ ti mo da ni siyi jẹ ki nniran aṣeye ọjọ'bi ti ọrẹ mi Ọgbẹni J. Modupẹ Johnson (ẹniti gbogbo nyin mọ ni J.M.J. jake-jado Nigeria) ṣeṣe ṣe n i n u i l e rẹ n i Apapa Ajegunlẹ.

Mo wa ri daju gbangba wipe eto ARỌJUNA'WO (austerity measure) ti Ijọba da sile, tọmọde tagba, ati ọmọ awo a t i ọmọ ọgbẹri ni eto na bawi, nitoripe enia mi kan ti o wa si Apapa Ajegunlẹ lọjọ na ni orin, "Bi Jesu ba ṣọwa damọdun ...... ni wọn kọ titi. Emi Ayiluka wa fi ẹsẹ orin ti o ku ninu orin na k u n fun u bayi: "k o sọti nibẹ arayẹn ! arayẹn !! arayẹn !!! ko sọti nibẹ. Bi Jesu ba ṣọwa damọdun ko sọti nibẹ".

- Bẹni adọta ọdun ki iṣe ọmọde ọjọ rara. Eyi mumi ranti igba ti a nda iyẹpẹ si ara wa lara nigba kekere, ni I t a ADANUN, lọjọ ti a nfi abẹrẹ yan jiga lẹsẹ, lọjọ ti a nlọ gun igi-kaju onikaju. kakiri loko oloko ninu igbo Ikoyi; o mu mi ranti iwa-ipata wa ninu ọkọ OKOKO-MAIKO. o mu mi ranti ọpọlọpọ oko-biriki ti a ti sọlu aja alaja ati ologbo olologbo ti awọn ti nderuba wa ni Ita Adanun ati ninu ọgba Padi. Modupe, o ku orire, aṣeyi ṣamọdun o.

TIṢA LUCAS, Ẹ KU O.

Mo gbọ wipe Olukọ mi atijọ, Ẹniọwọ Alufa J. Olumide Lucas, alufa Ijọ Ṣọṣi Bẹrẹfurutu l'Eko binu fi iṣe na silẹ ko buru, nkan ti aja yio jẹ ogun ti ṣe e. Bi Ẹniọwọ w a n a ko ba le lọ p'ago si Agege ki o lọ si abule Ẹgba tabi abule Jibowu ni OJOKORO leti oko Oba ni Agege, ki o ma gbadura fun wa gẹgẹbi ti Ologbe Ẹni-Ọwọ Alufa T.A.J. Ogunbiyi ti ma nṣe nigba aiye rẹ ni Ikẹja. Mo le w a ẹni meji mẹta tabi mẹrin kunra lati d'awo Ṣọṣi kekere ati owo-apo alufa fun ilunrere titun na.

Emi Ayiluka si t i t u n ṣ e t a n lati b a nyin wa awọn ọmọ ile-ẹkọ fun ẹkọ-idẹra b i ẹ b a l e ṣ e akinkanju lati ma kọ wa bi a ti nṣe otitọ ati ododo nile, lọna a t i loko, ki ẹ si ma jawa lọrẹ lasiko-lasiko, bi ẹ ti ma nja wa lọrẹ nigbati ẹnyin ati Alufa E. J. Evans pelu Ẹniọwọ A.B. Hobson ti ma nja wa lọrẹ ninu ile-iwe giga (C.M.S. Grammar School) l'Eko, niwọn ọdun mejilelọgbọn sẹhin. Alagba, ṣugbọn agba ṣẹ nde ko si aye a nsare sihin a nsare sọhun mọ. Mo ki nyin, ẹ o lo isinmi na pẹ, ki ẹ ba mi k i R o n k ẹ o.

## Alatise Nio mo Atunse ara re

O bẹrẹ lati oju ewe kẹta

Adio tun pe iyawo keji, o tun bere imọran 'ọwọ rẹ, imọran ti iyawo keji nipe, ki Adio maṣe mu ẹiyẹ kekere silẹ rara o, nipa bayi nkọ, iṣan ara ọkọ on yio le ṣiṣẹ daradara.

Wo iyoku loju ewe keje

# A s a r e Bi Ategun



Osere idaraya Derek Ibbotson, ọ m ọ ọdun mẹtadin-lọgbọn, ti o jẹ ọmọ i l u Gẹsi ti o yege ninu ere ije sisa lori ibuṣọ mẹta n i Wembley, n i l u nla London larin iṣẹju mẹtala si mẹrinla laipẹ yi.

Ọgbẹni Ibbotson ti o yege ere busọ mẹta yi, ni o ti kọkọ yege ibusọ meji ṣaju e y i ti o fi gba'we oṣere ere ibusọ.

## Itumo Alo !

1. Alantakun
2. Ọsun
3. Odo
4. Atare
5. Agbara - Ojo
6. Ọmọ ika ọwọ
7. Ijalọ
8. Olu
9. Igbọnsẹ
10. Ogun'na.

# Fo Soke, Ja Lule Ni Ere Bolu Afesegba.



Ę wo Asole Tony Macedo ti egbę Fulham, bi o ti yi lulę lati le mu bolu ti Fred Pickering ti egbę Blackburn Rover fę gba ti o fo soke ki o ma ba ta ęniti o yi lulę ni'pa.

Ọmin ni nwọn gba bọlu na.

## Omo'ba Onishua Ti ılu Oyinbo De

Ni ọjọ Wednesday ọsẹ to kọja ni Ọmọba'binrin Adetọla Adesunloye, tişe ọmọ bibi inu Ọba Adesunloye, Olishua ti ilu Ishua, Alaga ile işę itęwe ipinlę Iwọ-orun nilu Ibadan, ba ọkọ oju omi (Auroel) gunlę siluEko ni Apapa lati ilu Oyinbo lęhinti o ti yege ninu işę akọwe ti o lọkọ.

Awọn Ęb', ọrę, ibatan ati ọpọlọpọ ojulumọ ni o wa pade rę pęlu Alaiyeluwa Ọba Olishua ni ori Kereni ọkọ ni Apapa, nwọn ko si mọto d'oriko Ile isin ti enia dudu (U. N. A. Church) fun adura idupę lọdọ Ọlọrun. Alufa ile isin na şe aponle ọmọba Adetọla Adsuloye pupọ lori ękọ rę ti o yege

Alayeluwa Ọba Olishua gba awọn ębi rę ati awọn Ọba ati Ijoye ti o wa lati ipinlę Iwọ-orun l'alejo sinu ile onję, ni Apapa lọjọ na. Ọmọba fi Eko silę pęlu baba rę lọ si Ibadan lalę ọjọ kanna.

## Alo o? Alo!

1 Igbo ti o gba ọmọ erin, ti o si gba ọmọ'ęfọn, ọmọ ajantala kọja ni ibę o fi iwo kọ igi.
2 A ba baba l'oju ọna, o ni ki a ma a ho mudunmudun ori on ję.
3 Ewura gędęgbę a bu u ko l'oju.
4 Ọba alaran fi epa ępa ru igbę eebu.
5 Ogboju onisegun gba iwaju ile Ọba wọle, o gbehinkule lade.
6 A bę l'ori bę nidi o nyin mu.
7 Awọn ọmọ babalua mi kan lailai, awọn ọmọ babalua mi kan lailai, ti nwọn ba nlọ si ogun, gbogbo wọn a ma a sufe.
8 Onirọ aiye, onirọ ọrun, o şu oşuka rę bę tę, o ni on yio gbe ile ru.
9 Ọpę baba mi kan lailai ọpę baba mi kan lailai, a ki ro aşo gun un, a ki irın ikoho gun, a ko si le şe ki a ma gun un.
10 O nku lọ o npariwo.

## AWỌN ỌMUTI MEJI PARAWỌN S'OKO ĘLĘMU

AKURĘ - Laipę yi ni awọn ọdọmọkunrin ọkuọmuti meji ti orukọ wọn nję Raimi Fọlọrunshọ, ęni ọdun marundinlogoji ati Dahunsi, ęni ọgbọn ọdun, pa ara wọn nitori edeaiyede lori şile męjọ ti wọn ni ęnikan gbe l'apo şokoto Fọ lọrunshọ ninu ile ti nwọn jọ ngbe

Onirohin wa fi ye wa wipe ni ọjọ ti ọrọ na şelę Fọlọrunshọ ni şile męjọ ti nwọn ji gbe ninu apo şokoto on, on fura si ọrę on Dahunsi wipe on l'ogbe. Dahunsi ni on ko mọ nkankan nipa rę, epe ti o ba ri o le şę fun ęniti o gbe owo na.

Nwọn fi ọrọ yi logun nwọn fi lọgbọn, nwọn ni ti o ba di ọjọ keji ki awọn pade loko ęlęmu awọn, ki awọn fi ọkunrin han ara wọn. Nitotọ nitotọ nigbati nwọn de oko na, lọjọ keji, nşe ni nwọn bęręsi şa ara wọn l'ada, ni awọn mejeji ba pa ara wọn silę bi oku agbọnrin.

Awọn ọlọpa ti pe bale wọn, Belo Adebisi, pe ki o wa sọ nkan ti o ba mọ nipa ọrọ na.

# Omin L'ayo Na



AWỌN ẹgbẹ agba-bọlu af'ẹsẹgba, ti Aṣọle ti Cardiff (Collie) Vearncombe lu gbadi ihamọ lati gba bọlu kuro pẹlu asiwaju ti Arsenal, Strong (N0. 9.) ati ọmọ ẹgbẹ ti Cardiff paapa Mel Charles (N0. 6.) ti nwọn gba lọdọ Arsenal laipẹ yi.

Akatakiti yi ṣẹlẹ nibi ere bọlu ti nwọn gba nile Arsenal ti o jasi ọkọkan (1-1) ọmin.

## Alatise Nio mo Atunse ara re

O bẹrẹ loju ewe kẹta

Igbati Adio gbọ imọran awọn mejeji, ko mọ eyiti yio ṣe mọ, igba yi gan ni o wa ronu ara re wo pe "Alatiṣe ni yio mọ Atunṣe ara rẹ". Adio wọ inu iyẹwu rẹ o kunlẹ, o d'oju bo ilẹ, o bẹrẹ si ke pe Ọlọrun rẹ pe Iwọ Ọlọrun, Iwọ l'oda mi, maṣai yọ mi ninu adanwo na, ohun ti emi yio ba ṣe nibẹ, jọwọ maṣai fi ye mi, Ọlọrun fi ye mi. Oluwa si gba adura rẹ.

O sọ fun pe kio lọ ra ẹiyẹ kekere miran kio fi sinu apo ọtun, lẹhin bẹ kio wa sọ fun ẹiyẹ nla pe kekere to wi ni yi o. Kio wa ju silẹ bi ọwọ rẹ ba le tẹ nigbana o ku si ọwọ wọn.

Bayi ni Adio lọ ra ẹiyẹ na, o si ju silẹ, were bo ti ju ẹiyẹ to re ni oju Adio ha la, lẹhinna ni o mu ẹiyẹ kekere jade lapo ti o si pe kio ma lọ ni alafia, bi ẹiyẹ na ti bọ sita, ni iṣan idi rẹ di alagbara, nipa bayi ni ọkunrin yi fi ri igbala lọdọ Ọlọrun nigbati o da ọgbọn inu ara rẹ.

Lati ọjọ na ni Adio ti yi oruko rẹ pada si 'Alatiṣe ni yio mọ atunṣe ara rẹ".

Lọsẹ to mbọ, ẹ ma ṣbadun mi siwaju si, o digba kan na o.

# Awo'rawo

Eyi ni ohun ti yio ṣẹlẹ larin ọsẹ ti o mbọ.

Dec 23 - Jan 20 -(CAPRICORN)

Maṣe da ṣe nkankan. Ma a ba awọn enia k'ẹgbẹ pọ, ki o si ma a gba imọran.

Jan 21-Feb 19-(AQUARIUS)

Asiko yi dara fun ọ pupọ lati ṣe iṣẹ ati pẹlu wa jere pupọ, wa si ni orire ninu ori-ire larin ọsẹ yi.

Feb 20-Mar 20-(PISCES)

Owo pupọ yio to ọ lọwọ ni ọsẹ yi, iwọ yio si ri adanwo pupọ bakanna. Ọrẹ rẹ timọtimọ yio fun ọ ni imọran, gbọ ohun to ba wi fun ọ, ma ṣe na inakuna ki o si fi owo pa mọ.

Mar 21-April 20-(ARIES)

Ẹnikan ti ko to ọ fẹ fi ọbẹ ẹhin jẹ ọ ni iṣu nitorina ṣọra gidigidi. Ṣugbọn wa ri ẹbun gba pupọ

April 21-May 22-(TAURUS)

Ọpọlọpọ wahala wa fun ọ ṣugbọn ẹniti o ko ni ero si yio ran ọ lọwọ.

May 23-June 21-(GEMINI)

Asiko yi dara fun ọ lati rin irin-ajo tabi lati ma lọ si ibi aṣeyẹ. Iwọ yio ba awọn enia pataki ti yio ṣe ọ ni anfani pade, nwọn yio si fẹran rẹ pupọ.

June 22-July 22-(CANCER)

Ṣọ ara rẹ lọdọ alabosi tabi oninufufu kan. Ki o si ṣe suru pupọ lasiko yi.

July 23-Aug 22-(LEO)

Ṣe gbogbonkanti o ba fẹ ṣe leto leto pẹlu ifarabalẹ, owo yio si tẹ ọ lọwọ ni ọsẹ yi.

Aug 23-Sep 22-(VIRGO)

Aṣọ oriṣiriṣi ni ki o lo larin ọsẹ yi, yio si ṣe ọ ni anfani. Iwọ yio rin irin ajo eyiti iwọ yio ri ọpọlọpọ ẹbun gba.

Sep 23-Oct 22-(LIBRA)

Ọpọlọpọ nkan ni yio ṣẹlẹ si ọ ni ọsẹ yi. Yara tete mọjuto wọn fun anfani re. Ọsẹ yi dara fun ọ pupọ ju.

Oct 23-Nov 21-(SCORPIO)

Iwọ yio ri obirin gbajumọ kan ti yio ran ọ lọwọ de aye ti iwọ yio ri igbega pupọ, ṣugbọn ma ṣe ba enia ṣe gbolohun asọ.

Nov 22-Dec 22-(SAGITTARIUS)

Iwọ yio ba enia pataki kan sọrọ lori ohun pataki kan, yio si yọri si rere. Bi o ba wọ ọkọ omi sọda ni iwọ yio ṣe alabapade oluwa rẹ.

# OLOPA NWA AWON GBOMO-GBOMO KAN KIRI

IBADAN - Ni ọjọ Satide ijẹjọ ni ọmọdebinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Juliana Ọmọlolu, ara Modakẹkẹ ni Ile-Ifẹ sare wọ ile iṣẹ awọn ọlọpa ti o si nmi hele-hẹlẹ, ti o ni nṣe ni on sa lọwọ awọn gbọmọ-gbọmọ kan ti nwọn fẹ fi on ṣẹ'ṣo.

Ọmọdebinrin na ni lọjọ Jimọ ti o kọja ni iya on ran on ni iṣẹ lọ si ọdọ baba kan ti o njẹ Johnson Ayinde ti o ngbe Opopo Akarabata ni Ile-Ifẹ, nigbati on de ibẹ on ba awọn ọkunrin meji ninu iyara kan, nwọn ni ki on rii ọwọ on mejeji sinu ikoko agbo kan ki on si fi bọ oju. O ni bi on ti ṣe eyi tan ni on ri pe ara on ko jẹ t'on mọ.

O niwara-nṣeṣa, nwọn ti gbe on sinu mọto ayọkẹlẹ kan, nwọn si ru on wa sinu ile kan ni Ibadan nibiti nwọn gbe ti npalẹmọ ti nwọn fari ori fun on lati ṣe ṣawura on ni iye ba sọ si on l'ọkan, ni on ni ki nwọn jọwọ jẹki on ṣe nkankan lẹhinkule wọn, o ni ni ibẹ ni on ti tu piri mọwọn lọwọ.

Awọn ọlọpa nwadi ọrọ na nisisiyi.

## Agbako Ori-Ede, Omo Ku Lojo Ikomo

IBADAN - Laipẹ yi ni ọkunrin kan Lamidi Ologun, ni Alafara, ṣe ikede fun awọn ọrẹ ati ọmọlẹbi rẹ wipe on fẹ ṣe ikomọjade ọmọ-titun ti iyawo on ṣẹṣẹ bi fun on. T'ọkọ-t'aya wọn fi ile pọn ọti nwọn fi ọna r'oka.

Ninu nwọn nṣe aṣeyẹ ikomọjade yi lọwọ, ti ilu si ndun kikan-kikan ni nwọn ṣe akiyesi pe ọmọ - titun na nke nibiti iya rẹ gbe tẹ si. Nigbati nwọn yẹ ibẹ wo, nwọn ri i pe ejo kekere kan ti o sapamọ si abẹ aṣọ ni o buje, ki nwọn to ru ọmọ na de ile alaisan ni Adeọyọ, o ti ku, iya ọmọ paapa si daku lọ gbọnrangandan, awọn Dokita si ṣe ọlọjọjọ rẹ fun bi ọjọ mẹta, ki o to bọ si'po.

## Ijoba Ko Owo Atijo

Irohin pataki kan tẹ awa Oniwe irohin Eleti-Ọfẹ lọwọ loru ana, pe lati ọjọ kinni osu keje ọdun yi, ẹnikẹni ko gbọdọ na owo kọrẹnsi (old West African currency notes) ti Ijọba atijọ mọ. Ẹnikẹni ti o ba na owo kọrẹnsi na lẹhin ọjọ ti awọn alaṣẹ ile-ifowo-pamọ-si wi yi, nwọn ko ni gba awọn owo na lọwọ wọn.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; Olotu L. A. OJO, 12 Inabere Street, Lagos.

Nitorina, Eleti-Ọfẹ gba nyin ni imọran, ẹnyin ti ẹ nri owo mọlẹ, ki ẹ tete mu awọn owo atijọ ti o ba wa lọwọ nyin lọ si Banki, ki nwọn parọ rẹ fun nyin.

## Boisson Honours Brossette

Quite a lot of people including diplomats, chiefs and businessmen were at the Federal Palace Hotel last Saturday, in response to the invitation of Monsieur Boisson De Chazownes, Business manager of Messrs Brossette (Nigeria) Ltd, to a reception in honour of Monsieur Henry Brossette, chairman of the company who visited Nigeria on a business tour.



Picture shows from left Mr. Taju Thompson Monsieur Henry Brossette, Mr. Alex. Ola. Oni and Monsieur Boisson at the party.

## Nigerian Journalist To Tour Britain

Mr. Mike Pearse, north regional editor of the Nigerian Daily Express, is to spend six months in Britain as one of a party of nine Commonwealth Journalists under the Commonwealth Press Union Fellowship Scheme.

Arriving in Britain on 6th May, the party will see many aspects of the British way of life before the end of their visit in October.

A helicopter-eye view of London, an insight into police methods of training dogs, a dawn visit to London's famouse fruit and vegetable market at Covent Garden, Derby Day at Epsom and a tour of the Royal Horticultural Society's world-renowned Chelsea Flower Show are among the high spots of a busy programme arranged by the Central Office of Information for their first month in Britain.